YORÙBÁ GBÒDE

FỌL. 3, NỌ. 4, 2004

Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà



Yorùbá Gbòde

FỌL. 3, NỌ. 4, 2004

Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà

National Journal of the Association of the Teachers of Yorùbá Language and Culture of Nigeria.



© Ẹgbẹ́ Akọ́mọ̀lédè àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà 2004
(Association of the Teachers of Yoruba Language and Culture of Nigeria)

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced or transmitted in any form or by any means without permission.

First Published 2004

ISSN 1118 - 2482

Direct all enquiries to:

Bísí Oyèwọ̀lé
Department of Nigerian Languages
Kwara State College of Education
P.M.B. 1527 Ìlọrin
Kwara State.

Produced for the Association by

MACMILLAN NIGERIA PUBLISHERS LTD.
Ilupeju Industrial Estate
P.O. Box 264, Yaba, Lagos
P.O. Box 1463, Ibadan
Companies and representatives throughout the world.

Printed by Foludex Press Limited, Ibadan

Ìtọ́ka Àkóónú

Ìtọ́ka Àkóónú iii
Ìgbìmọ̀ Àpapọ̀ Ẹgbẹ́ fún Ọdún 2002-2004 iv
Àwọn Ìrírí-Dọgbọ́n iv
Ìgbìmọ̀ Aṣètò *Yorùbá Gbòde* v
Kére o! vi
Àníyàn Ẹgbẹ́ vi
Ọ̀rọ̀ Olótùú vii
Àwọn tó lọ́wọ́ nínú kíkọ Fol. 3, No. 4 viii
1. Kíkọ́ Ìbéèrè Èwo-Nìdáhùn ní Àkọ́yege fún Ìdánwò Àṣekágbá (S.S.C.E) — *Sulaimon Àdió Àlàó* 1
2. Kíkọ́ Aáyan Ògbufọ̀ (Gẹ̀ẹ́sì sí Yorùbá) ní Àkọ́yege fún Ìdánwò Àṣekágbá (SSCE) — *Olúwatúsìn Samson Fọ́lọ́runṣọ́* 11
3. Ipa àti Ipò Èdè nínú Isẹ́ Alátinúdá Yorùbá: Ẹsẹ Àkọ́kọ́ — *Bísí Oyèwọlé* 16
4. Ayọ̀ Ológunlékòó kú! — *Níkẹ̀ẹ́ Aya Adámọlẹ́kun* 25
5. Síso Ilé-Isẹ́ Ìjọba di ti Aládàáni: Èrèjẹ àti Àdánù — *Kẹ́hìndé Àkàngbé* 27
6. Kíkọ́ Gírámà Yorùbá ní Àkọ́yege fún Ìdánwò Àṣekágbá (SSCE) — *Ògúnkúnlé, A. Ọláolúwa* 30
7. Ìlò Oríkì Nínú Ìwé Ìròyìn Yorùbá — *Táíwò Olúnládé* 37
8. Ìṣèlú, Ìlò Oògùn àti Ìbáyému Abàmì nínú *Orílawẹ̀ Àdìgún* tí Afọlábí Ọlábímtán kọ — *Lérè Adéyẹmí* 62
9. Àgbéyẹ̀wò Adébóyè Babalọlá gẹ̀gẹ́ bí Akéwì Yorùbá — *Hamzat S.A.O.* 75
10. Gbàjarè! Akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá ń fidí rẹmi púpọ̀ — *Adémọ́lá Ọdẹ́tókun* 86
11. Kíkọ́ Ètò Ìró Èdè Yorùbá ní Àkọ́yege fún Ìdánwò Àṣekágbá (SSCE) — *Ọmọọba Bísí Adésígbìn* 93
12. Kíkọ́ Aáyan Ògbufọ̀ (Gẹ̀ẹ́sì sí Yorùbá) ní Àkọ́yege fún Ìdánwò Àṣekágbá (SSCE) — *Ìbítóyè Kẹ́mi Fọlásadé* 98
13. Kíkọ́ Àròkọ ní Àkọ́yege fún Ìdánwò Àṣekágbà (SSCE) — *Olúṣíji Babátúndé* 109
14. Déètì Nílẹ̀ Yorùbá Lójọ́ Ọjọ́un — *Àyìndé Abímbọ́lá* 117
15. Conference Communique 124

Ìgbìmọ̀ Àpapọ̀ *Ẹgbẹ́ Akọ́mọ̀lédè Àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà* fún Ọdún 2002 - 2004

Àwọn Olóyè Ẹgbẹ́ :

1.	Àárẹ	-	Túndé Ẹkúndayọ̀
2.	Igbákejì Àárẹ	-	Oyin Aya Ọnàṣílé
3.	Akọ̀wé	-	Díákónì M.A. Olówu
4.	Igbákejì Akọ̀wé	-	Bọ́lá Aya Ọ̀rọ̀gún
5.	Akọ̀wé Owó	-	Ayọ̀délé Matthew
6.	Igbákejì Akọ̀wé Owó	-	Z.A. Fádìtàn
7.	Akápò	-	Fúnnṣọ́ Fọlárànmí
8.	Akọ̀wé Ìkéde	-	Kúnlé Jimoh
9.	Ayẹ̀wé-Owó-wò	-	Àkànjí Ismaila
10.	Ayẹ̀wé-Owó-wò	-	Àtàndá James Ọláwálé
11.	Olótùú *Yorùbá Gbòde*	-	Bísí Oyèwọlé

Àwọn Ìrírí-Dọgbọ́n

Ìpínlẹ̀ Èkó	-	Olóyè Bọ́lá Àjàyí
Ìpínlẹ̀ Kogí	-	Alàgbà S.K. Moody
Ìpínlẹ̀ Kwara	-	Ọmọ-ọba Agboọlá Abọ́lárìn
Ìpínlẹ̀ Ògùn	-	Alàgbà Olúṣẹ́gun Ògúnfọlájì
Ìpínlẹ̀ Ondó	-	Alàgbà Délé Alóńgẹ́
Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́	-	Alàgbà Sọlá Ògúntọ́pẹ́
Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun	-	Alàgbà Bísí Àmọ̀ó
Ìpínlẹ̀ Èkìtì	-	Olóyè Délé Àjàyí
Ìlà-oòrùn	-	Alàgbà Gòkè Owólabí
Ìhà-Àríwá	-	Alàgbà Olúwatúsìn Fọ́lọ́runṣọ́
FCT	-	Alàgbà O.S. Sàlámì

Ìgbìmọ̀ Aṣètò *Yorùbá Gbòde*

Olótùú Gbogbogbòò
Alàgbà Bísí Oyèwọlé
Dept. of Nigerian Languages,
Kwara State College of Education, Ilọrin, Kwara State.

Olótùú
Alàgbà Adéníyì Àkàngbé
Macmillan Nig. Publishers Ltd.,
P.O.Box. 1463, Ibadan.

Àwọn Igi-lẹ́yìn-ọgbà Olótùú

Alàgbà Túnjí Ọ̀pádọ̀tun
Dept. of Nigerian Languages,
Oyo State College of Education,
Oyo.

Alàgbà Táíwò Olúnládé
Dept. of African Languages,
Literatures and Communication Arts,
Lagos State University,
Ọjọ, Lagos.

Olùdámọ̀ràn Yorùbá Gbòde

Ọ̀jọ̀gbọ́n Olú Àlàbá
Dept. of African and Asian Studies, University of Lagos,
Akoka-Lagos State.

Ọ̀jọ̀gbọ́n Bísí Ògúnṣínà
Dept. of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilọrin,
Ilọrin, Kwara State.

Alàgbà Adémọ́lá Ọdẹ́tókun
Dept. of Nigerian Languages,
Kwara State College of Education,
P.M.B. 1527 Ilọrin,
Kwara State.

Alàgbà Fẹ́mi Dágundúró
Tai Ṣolarin College of Education,
Ìjẹ̀bú-Òde,
Ògùn State.

Kére O

Èyí ni láti fi tó gbogbo onífẹ́ẹ́ ìmọ̀ létí pé *Yorùbá Gbòde* ṣetán láti máa gbé àbọ̀ ìwádìí yín jáde lóòrèkóòrè. Irú ìwádìí bẹ́ẹ̀ sáa gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí a kọ lédè Yorùbá. Ó lè jẹ́ èyí tí a kọ lórí ìmọ̀ ìṣègùn, ìmọ̀ kọ̀ǹpútà, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì, àṣà, èdè, ìṣesí àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ lórí ìrònú Yorùbá.
Kò sí òfin mìíràn ju pé kí ó tẹ̀lé ìlànà àkọtọ́ Yorùbá òde-òní pẹ̀lú kíkọ àwọn ìwé ìtọ́kasí (àwọn ìwé tí a yẹ̀wò) ní ìlànà *APA*. Kí gígùn rẹ̀ má ju ojú-ìwé mẹ́wàá lọ (quarto size) pẹ̀lú àwọn ìwé tí a yẹ̀wò. Fi átíkù rẹ ránṣẹ́ sí:

Bísí Oyèwọlé (Olótùú Gbogbogbòò)
Department of Nigerian Languages,
Kwara State College of Education, Ilọrin.

Àníyàn Ẹgbẹ́

1. Kí gbogbo àwa Olùkọ́ni lè parapọ̀ gégẹ́ bí Ẹgbẹ́ Olùkọ́ni ní Èdè Yorùbá.
2. Kí èrò àti ètò àwa Olùkọ́ni lórí ohun tí a ó kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè jẹ́ ọ̀kan náà.
3. Kí ọ̀nà tí a ó fi máa kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè báramu jákèjádò ilẹ̀ wa lórí ìpilẹ̀ṣẹ̀ tí ó yẹ kooro nítorí èyìn ọ̀la.
4. Kí àjọṣe àwa àti àwọn olùdarí ètò ẹ̀kọ́ ti ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan àti àwọn àjọ olùdánwò gbógbogbòò lè báramu.

Ọ̀rọ̀ Olótùú

Kíkọ́ Èdè Yorùbá ní Àkóyege fún Ìdánwò Àṣekágbá Ilé-ẹ̀kọ́ Sẹ́kọ́ńdìrì Àgbà (WASSCE/NECO SSCE) ni kókó àpérò ìpàdé gbogbogbòò ti ọdún 2003 tí a ṣe ní Abẹ́òkúta Grammar School, Ìdí-Àbà, Abẹ́òkúta ní Ìpínlẹ̀ Ògùn dá lé lórí. Àwọn àṣàyàn pépà tó pegedé lórí ọ̀kan-ò-jọ̀kan àtúnpín kókó àpérò yìí ni àkànṣe Jọ́nà *Yorùbá Gbòde* yìí dá lé lórí.

Àwọn àtúnpín kókó ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni Kíkọ́ Ìbéèrè Èwo-nì-dáhùn, Àkàyé, Àròkọ, Ètò-Ìró Èdè, Gírámà àti Aáyan Ògbufọ̀. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àfikún àwọn pépà mìíràn tí a mọ̀ pé yóò ṣe àfikún ìmọ̀ fún tolùkọ́ takẹ́kọ̀ọ́.

A gbé òṣùbà ńlá fún ilé-iṣẹ́ aṣèwétà Macmillan fún ìpèsè jọ́nà ọdún 2004 fún ẹgbẹ́ lọ́fẹ̀ẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìṣe wọn àtẹ̀yìnwá. Ìgbìmọ̀ Aṣètò *Yorùbá Gbòde* àti Ẹgbẹ́ lápapọ̀ mọ rírì oore yìí. Ilé-iṣẹ́ yín kò ní bàjẹ́ o. Ìdùnnú wa ní yóò jẹ́ bí àwọn ilé-iṣẹ́ aṣèwétà mìíràn náà bá le máa ṣe ìrànwọ́ báyìí fún wa.

Láìṣe iyèméjì, ọgbọ́n òun ìmọ̀ tó kún inú jọ́nà yìí fọ́fọ́ yóò ṣe gbogbo ẹni tó bá kà á ní àǹfààní. Torí náà, ẹ tara ṣàṣà bu omi ọgbọ́n àti ìmọ̀ mu. A dúpẹ́ lọ́wọ́ ògbẹ́ni Adéníyì Àkàngbé ti ile-iṣẹ́ Macmillan fún àmójútó tí wọ́n ṣe nípa àtẹ̀jáde yìí. Ọdọ́dún leégún í jó, ọdọ́dún lorò í gbòǹà, ọdọ́dún lewé í rú, ọdọ́dún lewùrà í pewé, ọdọ́dún ni *Yorùbá Gbòde* yóò máa gbòde o. Tolórí tẹlẹ́mù wa ò ní pọ́dún jẹ o; àṣẹ.

Bísí Oyèwọlé
Olótùú Gbogbogbòò

Àwọn tó Lọ́wọ́ Nínú Kíkọ Fol. 3, Nọ. 4

1. Sulaimon Àdìó Àlàó — P.O. Box 8273, Ṣomolu, Lagos
2. Olúwatúsìn, S.F. — Federal College of Education, Okene, Kogi State.
3. Bísí Oyèwọlé — Kwara State College of Education, Ilọrin.
4. Níkẹ́ẹ́ Aya Adámọlẹ́kun — Federal Government Girls College, Àkúrẹ́.
5. Ògúnkúnlé, A. Ọláolúwa — C & S College, Ilọrin, Kwara State.
6. Táíwò Olúnládé — Department of African Languages, Literatures and Communication Arts, Lagos State University, Ọjọ́, Lagos State.
7. Lérè Adéyẹmí — Department of Linguistics and Nigeria Languages, University of Ilọrin.
8. Hamzat, S.A.O. — Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilọrin.
9. Adémọ́lá Ọdẹ́tókun — Kwara State College of Education, Ilọrin.
10. Ọmọọba Bísí Adéṣígbìn — Ìwó, Ọṣun State.
11. Ìbítóyè Kẹ́mi Fọlásadé — Bọ́ládé Senior Grammar School, Bọ́ládé Oṣòdì, Lagos State.
12. Olúṣíji Babátúndé, — College of Education, Ìkẹ́rẹ́-Èkìtì.
13. Àyìndé Abímbọ́lá — Department of Curriculum Studies, Faculty of Education, University of Lagos.

ÀGBÉYẸ̀WÒ ADÉBÓYÈ BABALỌLÁ GẸ̀GẸ́ BÍ AKÉWÌ YORÙBÁ

Hamzat S.A.O.
Ìpínlẹ̀ Kwara

Ìfáárà

Àkójọpọ̀ ewì Adébóyè Babalọlá tí a rí nínú Ìwé *Ewé Ọ̀mísínmisín* ní a gbà pé ó ti bẹ̀rẹ̀ láti ọdún 1950 tí ó ti ń fi ewì dánra wò nínú ìwé ìròyìn Yorùbá títí ìwé yìí fi di títẹ̀ jáde ní ọdún 1989. Tí a bá wo àkóónú, ìlò èdè àti àgbékalẹ̀ ewì rẹ̀ a rí i pé kò le koko, pẹ̀sẹ̀ ló rọ̀ bí ẹni tí ń tàkurọ̀ sọ. Àwọn òdiwọ̀n tí àwọn onímọ̀ bí Aristotle, Plato, Coleridge àti Ọlátúnjí fún ewì bẹ̀rẹ̀ láti orí kókó ọ̀rọ̀ àgbékalẹ̀ títí dé orí ìlò èdè fẹ̀rẹ̀ má lè jẹ́ kí á pe ewì Babalọlá ní ewì. Ọlátúnjí (1995:337) tilẹ̀ tọ́ka sí i pé ìtumọ̀ àwọn ewì àpilẹ̀kọ Yorùbá ti máa ń lọ tàárà jù, kò fara sin nítorí náà wọn ò lè dúró ní ẹ̀gbẹ́ ewì Yorùbá tí Fẹ́mi Fátọ́ba ń kọ.

Ìtumọ̀ àkànlò tí Ọlátúnjí (1995:33) fúnka mọ́ yìí ló mú wa wo òdiwọ̀n ewì, èdè ewì àti akéwì, láti ṣe àyẹ̀wò ewì Babalọlá gẹ̀gẹ́ bí akéwì Yorùbá. Ǹjẹ́ Adébóyè Babalọlá yege òdiwọ̀n akéwì Yorùbá, ṣé ó tọ́ ní ẹni tí a le pè ní akéwì Yorùbá. Àwọn ìbéèrè tí a ó wá ìdáhùn sí nìyí ní ìparí iṣẹ́ yìí nípa fífi tíọ́rì sosíọ́lọ́jì lítírésọ̀ ṣe àtúpalẹ̀ ewì rẹ̀.

Aáyan Ọ̀mọ̀ràn

Ewì, Èdè Ewì àti Akéwì

Aristotle nínú Coulson (1981:18) pe ewì ní ìsínjẹ tàbí àwòjiji àwùjọ ṣùgbọ́n ìmọ̀ sosíọ́lọ́jì ti fi yé wa pé ewì tayọ ìsínjẹ tàbí àwòjìji nìkan, ó ń fa àyípadà ní àwùjọ pẹ̀lú. Ọ̀pọ̀ onímọ̀ ló gbà pé ewì gbọ̀dọ̀ jẹ́ àfiwé ẹlẹ́lọ́ọ́, kí ìtumọ̀ rẹ̀ ó farasin gẹ̀gẹ́ bí Aristotle nínú Coulson (1981:18) ṣe fi hàn. Èrò yìí kan náà ni Ọlátúnjí (1995:331) ń gbé yọ nígbà tí ó ń ṣe àtúpalẹ̀ ewì Fátọ́ba tí ó ní bí ó ti wù kí ó ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ ojoojúmọ́ tó ewì rẹ̀ o ṣe fún ní ìtumọ̀ eréfèé, pé ọ̀rọ̀ rẹ̀ kọ̀le ṣùgbọ́n ìtumọ̀ wọn farasin. Ìtumọ̀ àkànlò tí ewì Fátọ́ba ní yìí ni Ọlátúnjí ń pè fún látọwọ́ àwọn akéwì Yorùbá tí ó jẹ́ pé tàárà ni ìtumọ̀ ewì tiwọn máa ń lọ. A kò lè fúnka mọ́ èrò àwọn onímọ̀ wọ̀nyí pé ìtumọ̀ ewì gbọ̀dọ̀ fi ara sin. Àwùjọ tí akéwì bá fi ewì rẹ̀ sùn ni yóò sọ bí àfiwé rẹ̀ yóò ṣe lọ sí.

Ṣùgbọ́n òótọ́ ni pé ọ̀nà àrà ọ̀tọ̀ tí ó sọ̀wọ́n ni a fi ń gbé ewì jáde, ààtò rẹ a máa yàtọ̀ sí ti ọ̀rọ̀ wuuru, èdè rẹ̀ a sì máa dún yàtọ̀ bí Akínjọ́gbìn (1976:9) ṣe sọ. Ní èrò Plato bi Hamilton àti Huntìngton (1973:30) ṣe gbé e kalẹ̀.

Poetry is a speaking picture
Àwòrán tí ó ń sọ̀rọ̀ ni ewì

Èyí túmọ̀ sí pé ọ̀rọ̀ ewì ń ya àwòràn ìṣẹ̀lẹ̀ bí ẹni tí à ń wò ó lórí ìtàgé ni. Ewì tí a gbé yẹ̀wò yìí kó ògo oríkì Plato yìí já gẹ́gẹ́ bí a ó ṣe máa rí i ní iwájú'.

Oríṣìíríṣìí èrò ni àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n onímọ̀ ní lórí èdè ewì. Àwọn kan gbà pé èdè ewì yàtọ̀ sí èdè gbẹ̀ẹ̀fu tí a fi ń gbé ìtàn kalẹ̀ tàbí èdè ojoojúmọ́. Èdè tó rẹwa ni èdè ewì. Coleridge bí Coulsin (1981:18) ṣe fi hàn gbà pé ṣíṣe ààtò ọ̀rọ̀ tó yẹ sí ààyè tó tọ́ ni ewì, àtòjọ àkànlò èdè tí a kò le ṣe àgékúrú tàbí ìsọníṣókí fún mọ́ ni èdè ewì, èyí ò sì ní jẹ́ ká le mú akéwì mọ́lẹ̀ pé ọ̀rọ̀ rẹ̀ ò ju báyìí lọ. Aristotle náà gbà pé èyí ló ya akéwì sọ́tọ̀ láàrin oníṣẹ́ ọnà yòókù.

Gbogbo ohun tí wọ́n fi ṣe àpèjúwe èdè ewì la fara mọ́ ṣùgbọ́n a kò gbà pé àkànlò èdè tàbí àfiwé ẹlẹ́lọ́ọ́ gbọdọ̀ já ewi bíi kánhún jálasa. Ìlò èdè wà lọ́wọ́ àwùjọ tí akéwì bá dojú ewì rẹ̀ kọ, tó bá ṣe ọmọdé àti akẹ́kọ̀ọ́, èdè líle ò lè wúlò. A fara mọ́ èrò Coleridge tó sọ pé ìrònújinlẹ̀ ló ń fún ọ̀rọ̀ tàbí èdè ní ìtumọ̀ pé kíí ṣe ẹ̀wà tí a dá ró àfiwé àti àkànlò èdè. Òtítọ́ ibẹ̀ ni pé èdè tàbí kókó ewì nílò ìrònújinlẹ̀ ká tó mọ ìtumọ̀ rẹ̀.

A kìí déédé kọ ewì lásán láìjẹ́ pé nǹkankan gún ni ní kẹ́ṣẹ́ inú. Ọ̀rọ̀ lórí ohun tí ó ń gún akéwì ní kẹ́ṣẹ́ yìí ni Ìṣọ̀lá (1984:20) àti Fálétí nínú iṣẹ́ Sàngótóyè (1998:37) pè ní òrìṣà, tó ń gun òǹkọ̀wé. Coulson (1981:4) àti Jasper (1992:8) sì pèé ní ìmísí. Èyí fi hàn pé agbára kan máa ń gún àwọn akéwì ní kẹ́ṣẹ́ inú láti sọ ohun tó kún wọn lọ́kàn jáde. Ohunkóhun tí ó bá gún wọn ní kẹ́ṣẹ́ inú yìí ni a gbà ní òrìṣà tí ń gùn wọ́n. Ní èrò Fálétí, òrìṣà owó a máa gun akéwì, ìmọ̀ òde òní le gùn ún, ọ̀làjú àtọ̀húnrìnwá a máa gùn ún, bẹ́ẹ̀ sì ni ṣe-ká-rí-mi le gùn ún.

Tíọ́rì Sosíọ́lọ́jì Lítírẹ́ṣọ̀

Àwọn onímọ̀ sosíọ́lọ́jì lítírẹ́ṣọ̀ bíi Caudwell (1977:145); Milner (1978:48) àti Ògúnṣínà (1995:297) jẹ́ kí a mọ̀ pé ìrírí àti àyíká oníṣẹ́ ọnà ni ó ń pèsè èròjà iṣẹ́ ọnà. Ìrírí rẹ̀ nípa ètò ọrọ̀ ìṣèlú, ètò ajé àti

ibágbépọ̀ àwùjọ ló ń sí hàn wá tí ó sì ń sọ ihà tí ó kọ sí wọn. Wọ́n jẹ́ kí a mọ̀ pé lítírẹ́ṣọ̀ tayọ àwòjíji àwùjọ, ó ń wo sàkun ojọ́ iwájú (Duvignaud 1972:67), ó sì ń dá àbá àyípadà yálà lọ́nà ẹ̀rọ tàbí èlé.

Ngugi Wa Thiong'o bí Ògúnṣínà (1995:297) ṣe sọ ní:

> A writer responds with his total personality, to a social environment which changes all the time... for the writer himself lives in and is shaped by history.
>
> Ipò àti ipa òǹkọ̀wé ló fi ń sọ èrò rẹ̀ tàbí dá sí ọ̀rọ̀ tó ń lọ ní àwùjọ, èyí tí kò dúró ní ojú kan tí ó máa ń yípadà nígbà gbogbo... ara ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ni òǹkọ̀wé fúnra rẹ̀, ìṣẹ̀lẹ̀ inú itàn ló ń darí èrò rẹ̀ àti igbésí ayé rẹ̀.

Èyí ń fi yé wa pé àwùjọ ló ń ṣe atọ́kùn fún iṣẹ́ ọnà òǹkọ̀wé. Irú ìdàgbàsókè àti àṣà tí ó bá ń lọ lọ́wọ́ lọ́wọ́ ní àwùjọ ni yóó sọ ibi tí iṣẹ́ ọnà yóò darí kọ. Nítorí náà ipò Babalọlá àti àwùjọ rẹ̀ ní àsìkò ìgbé ewì jáde ni yóò nípa lórí irú kókó ọ̀rọ̀, àgbékalẹ̀ àti ìlò èdè rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akéwì lójú tiwa.

Fún ìdí èyí àmúlò tíọ́rì sosíọ́lọ́jì lítírẹ́ṣọ̀ ló bá àtupalẹ̀ ewì Babalọlá mu, òun ni yóò sì jẹ́ kí a mọ ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín ewì rẹ̀ àti àwùjọ rẹ̀.

Àjọṣepọ̀ Ìgbésí Ayé A. Babalọlá Pẹ̀lú Ewì Rẹ̀

Ara àwọn onífẹ̀ẹ́ èdè àti àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá tó ti ń fi ewì dánra wò ninú iwé ìròyìn bí Ògúnṣínà (1980:39) ṣe sọ ni Babalọlá wà. Ọdún 1950 ni ó bẹ̀rẹ̀ sí kọ ewì sínú iwé ìròyìn, àkójá ewé rẹ̀ sì ni "Àbúrò mi Gbínnísín (My Junior Brother) kí ó tó tẹ̀ ẹ́ jáde ní inú *Odù Journal of Yoruba and related studies* No. 1 ní ọdún 1956. Ọdún 1969 ni àwọn ewì rẹ̀ kan tún jáde nínú *Ewì Ìwòyí*. Iwé àtìgbàdégbà *Olókun* ló tún ti tẹ ewì rẹ̀ jáde láàrin ọdún 1970 sí 1975. Ọdún 1989 ló ṣe àkójọpọ̀ àwọn ewì rẹ̀ sínú iwé kan sáńgílítí tí ó pè ní *Ewé Ọmísínmisín*. Orí iwé yìí ni àgbéyẹ̀wò wa nípa Adébóyè Babalọlá gẹ́gẹ́ bí akéwì dá lé.

Láti ìbẹ̀rẹ̀ ayé rẹ̀ ni Adébóyè Babalọlá ti mú ẹ̀kọ́ iwé lọ́kùnkúndùn. Ó kàwé tán ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, ó tún lọ kà ní òkè òkun. Ìṣẹ́ olùkọ́ tó fi àárọ̀ ojọ́ rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ náà ló ṣe dọ̀jọ́ alẹ́. Ìmọ́rírì ẹ̀kọ́ iwé ló ń fi hàn ninú ewì "Ní kùtùkùtù ojọ́ kejìdínlọ́gbọ̀n oṣù karùn-ún ọdún 1948"(2) àti "Òkè Láńgbòdó ni mo rè" (41), tí ó fi sọ́rí Ọ̀gá ilé-iwé Igbóbì àti Kọ́fẹ́ṣọ̀ Fráùnsì Ótìlì ti Yunifásiti Òháyò ní Amẹ́ríkà, tí ó sì fi ń tẹnu

mọ́ ẹ̀kọ́ ìwé fún ọmọbìnrin yàtọ̀ sí àwọn òpònú èniyàn tí ń wá ọmọkùnrin pẹ̀lú ipá, ó gbà pé gbogbo lọmọ (15, 24).

Ìmọ̀ tó ti ní nínú lítírẹ́ṣọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì àti ti Yorùbá hàn nínú iṣẹ́ rẹ̀. Eré onítàn Shakespare *(Hamlet)* ló sọ di ewì Yorùbá tó pè ní ''Ìtàn ọmọ Ọba Hámúlẹ́ẹ̀tì'' (48). Ó lo ẹ̀bùn ìtàn pípa tó ní láti mú kí ewì náà jọ eré onítàn, ewì àti ìtàn pípa lẹ́ẹ̀kan náà. Ní inú lítírẹ́ṣọ̀ Yorùbá, ìtàn àròsọ Fágúnwà jẹ́ àwòkọ́ṣe fún un. Ìlànà ìṣíde ìtàn Fágúnwà hàn nínú ''Ní kùtùkùtù òwúrọ̀ Ọjọ́ kejìdínlógbọ̀n oṣù karùn-ún ọdún 1948'' (2). Bí Fágúnwà ṣe ń lo ọgbọ̀n àlá ni òun náà lò ó nínú ewì ''Àlá n mo lá'' (32). Ìsínjẹ Fágúnwà sì ni 'Òkè Láńgbòdó tí akéwì wá ìmọ̀ ẹ̀kọ́ lọ nínú ewì òkè Láńgbòdó ni mo rè'' (41). Òkè òkun ni òkè Láńgbòdó tirẹ̀ yàtọ̀ sí ti Fágúnwà tó jẹ́ inú igbó.

Àtúpalẹ̀ Ewì A. Babalọlá ní Ìbámu pẹ̀lú Tíọ́rì Sosiọ́lọ́jì Lítírẹ́ṣọ̀

Àwọn Ewì Ẹ̀sìn Rẹ̀

Ẹ̀sìn ni Ìgbàgbọ́ tí àwùjọ kan ní nínú ẹ̀mí àìrí kan tí wọ́n gbà pé ó lágbára tó sì ní ìkápá lórí ìgbé ayé àti kádárá àwọn, ẹ̀mí àìrí yìí ni wọ́n gbà pé ó ń ṣe olùdarí ìgbésí ayé wọn. Ẹ̀mí yìí le jẹ́ Ọlọ́run, òrìṣà, òjíṣẹ́ Ọlọ́run tàbí àfinúrò kan. Gbogbo lítírẹ́ṣọ̀ tó bá dá lórí ẹ̀mí yìí yálà ó ń gbé oríyìn fún un àbí ṣe àlàyé rẹ̀, tàbí ó dá lórí ìwé mímọ́ rẹ̀ ni a kà kún lítírẹ́ṣọ̀ ẹ̀sìn (Jasper 1992;3).

Ewì mẹ́rìndínlógún nínú mẹ́tàlélọ́gbọ̀n ni Adébóyè Babalọlá fi wàásù ìgbàgbọ́ ẹ̀sìn Kristi lọ́nà tàárà tàbí lọ́nà ẹ̀rọ. Ewì ''Kò ha kàn yín bí'' (6) ń bá àwọn tí kìí lọ sọ́ọ̀sì lọ́jọ́ ọ̀ṣẹ̀ wí, pé ìwà afọ́nú àti agbéraga ni wọ́n ń hù.

Èrò ìwà mímọ́ inú ìgbàgbọ́ Kristi ni ''Àlá n'mo lá'' àyàfi kí èniyàn ronúpìwàdà kó jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀. Ańgẹ́lì ló tilẹ̀ ń dá àwọn èrò inú ọkọ̀ tó ń ro èròkerò lẹ́jọ́, ní ìparí, ó ní:

> Ẹ jẹ́ n ran yín létí ọ̀rọ̀ Bíbélì
> ọ̀rọ̀ táa sọ fún gbogbo ẹ̀dá
> ''Lákòótán ẹ̀nyin ìjọ
> Èrò tíí ṣe ti òótọ́
> Àtèrò tíí ṣe tìwà rere
> Èrò báwọ́nyí ni ẹ máa fi ṣoge''. (37)

Ó gbìyànjú láti mú ìgbàgbọ́ Mùsùlùmí àti tẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọ inú ewì rẹ̀ nínú ''Ayé lọjà'' (67) ṣùgbọ́n Bíbélì ló tún fi ṣe àkàwé bí ẹ̀mí yóò ṣe padà sí ọ̀run lẹ́yìn ikú.

Àwọn ewì bíi ''Inajú Ìrọ̀lẹ́'',(1) ''Ọmọdé''(3) àti ''Ojú Ọjọ́ dára aya mi''(5) ló fi ń yin iṣẹ́ Ọlọ́run nípa títọ́ka sí ẹ̀wà àyíká ní ìlú Abẹ́òkúta àti ní òkè òkun láti gbóríyìn fún Adẹ́dàá. Ewì ''Ọmọdé''(3) ló fi ń sọ pé kádàrá Ọmọdé ń bẹ lọ́wọ́ Ẹlẹ́dàá, a kò mọ èyí tí yóò di ènìyàn pàtàkì láwùjọ nínú ọmọ tó rí ìtọ́jú àti èyí tí kò rí ìtọ́jú.

Ewì Ìṣèlú àti Ìwà Ìbàjẹ́ Àwùjọ

Gbogbo ohun tó ń lọ ní àyíká akéwì ni ó ń fi àròjinlẹ̀ wòye tó sì ń gbé èrò rẹ̀ kalẹ̀ lórí wọn. Àìdógba ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́, tolórí tẹlẹ́mù ni ewì ''Ayé ń lọ ní Mẹ̀lọmẹ̀lọ''(4) pẹ̀lú ''Ọkùnrin Apẹja kan''(18) àti ''Èyí ò yẹ kó rí bẹ́ẹ̀''(60) ń tọ́ka sí. Olùkọ́ ò lè ṣiṣẹ́ ọ̀mọ̀lé, bẹ́ẹ̀ni ọ̀mọ̀lé ò le ṣiṣẹ́ Olùkọ́. Tálíkà wà, kòlà-kò-ṣagbe ń bẹ, bòṣòkìnní ò sì lè ní kí Ọlọ́ṣọ́ kúrò ní ìlú, ṣùgbọ́n kí àwọn olóṣèlú ọmọ ilẹ̀ Áfíríkà sa ipá wọn lórí ètò ọrọ̀ ajé tí yóò mú ìdẹ̀rùn bá mẹ̀kúnnù. Ewì méta tí ó jẹ mọ́ ìṣèlú ló fi tako ìwà kò-kàn-mí tí àwọn olórí ìlú ń hù nípa ojú tí wọn dì sí ìyà tó ń jẹ mẹ̀kúnnù. Ọ̀nà èrò ni ó fi dá àbá pé:

> Dídù ló tọ́ kẹ́yin òṣèlú ó dù
> pé kàwọn aláìní òde òní
> ó di kòlàkòṣagbe pátá poo
> kí bòṣòkìnní ó wà síbẹ̀ bí ẹ̀wà
> kọ́lọ́ṣọ́ ó sì máa bẹ bí ẹ̀bẹ(19)

Lójú akéwì yìí gẹ̀rẹ̀jẹ̀ làá bágbà, yàtọ̀ sí ìwà ìbàjẹ́ ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ ara tí àwọn àgbà inú ewì ''Ohun tó bá yẹ ni ni ká máa lépa'' àti ewì ''Àjọṣe ẹbí''(46) hù, tí wọ́n ń torí ìfẹ́ ara fẹ́ ìyàwó àwọn ọmọ inú wọn. Ìtìjú ló mú bá aṣojú orílẹ̀-èdè ní Lọ́ńdọ́ọ̀nù. Ìwà yìí náà ló sì tú ẹbí nígbà tí Bàbá Ìrẹ̀sà sú ìyàwó àbúrò rẹ̀ lópó.

Ewì Ìfisọ́rí Ènìyàn àti Ayẹyẹ

Àwọn ewì rẹ tó fi sọ́rí ayẹyẹ tàbí ènìyàn ni ''Ní kùtùkùtù òwúrọ̀ ọjọ́ kejìdínlógbọ̀n oṣù karùn-ún ọdún 1948''(2). Ewì yìí ló fi sọ́rí Màmá Báyọ̀ tó ń ṣe ọjọ́ ìbí nítorí ó jẹ aya àtàtà lọ́ọ̀dẹ̀ọkọ, ó sì tún jẹ ìyá àtàtà fún àwọn ọmọ rẹ̀. Ó fi ''Òkè Láńgbòdó ni ó rè''(41) sọ́rí Kòfẹ̀sọ̀ Fraunsi Ótìlì tó jẹ Ọjọ̀gbọ́n àgbà nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì ní Yunifásítì Ọ̀háyò fún bí ó ṣe fi iwé ṣe ohun ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì tirẹ̀. Atẹ̀dùùrù ní Yunifásítì Èkó, Ayọ̀ Bánkọ́lé àti aya rẹ̀ tí Ikú pa lẹ́ẹ̀kan náà ló fi ewì rẹ̀ ''Àwa ń dárò Ayọ̀ Bánkọ́lé''(64) sọ́rí. Àwọn ọmọ Nàìjíríà ní òkè òkun ló fi ewì rẹ̀. Ọ̀rọ̀ Ìyànjú''(20) àti ''Mo Dúpẹ́''(21) bá wí. Kókó ọ̀rọ̀ rẹ nínú

ewì méjèèjì ni pé kí wọn ó má gbàgbé ilẹ̀ ìbí wọn àti èdè abínibí wọn nítorí èdè Gẹ̀ẹ́sì tí gbogbo wọn ń fọ̀ bí ọ̀pẹ̀ẹ̀rẹ̀ ò lè sọ wọ́n di Òyìnbó aláwọ̀ funfun.

Ìmọ̀ Èrò Ìjìnlẹ̀ Rẹ̀

Adébóyè Babalọlá gẹ̀gẹ́ bí olùsìn tòótọ́ ọmọlẹ́yìn Kristi ń gbé ìmọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ ẹ̀sìn lárugẹ. Kò pè fún àyípadà túláàsì nínú ewì ''Ọkùnrin Apẹja kan''(18) àti ''Èyí ò yẹ̀ kó rí bẹ́ẹ̀''(60) tó fi ń gba àwọn olóṣèlú ilẹ̀ Afirika nímọ̀ràn láti mú àyípadà rere bá ipò ẹ̀yìn tí àwọn mẹ̀kúnnù ilẹ̀ adúláwọ̀ wà. Ọ̀rọ̀ tútù ló fi ń la àìṣedéédé àwọn aláṣẹ ìjọba yé wọn, pé kí wọn ó ṣàtúnṣe káyé ó tù kó bà fún mẹ̀kúnnù (P. 61). Àpẹ̀jù tí aláìní pọ̀ nílẹ̀ Àfíríkà ló ń dun akéwì, àrọwà ló sì ń pa pé kí àwọn olóṣèlú ṣètò tí aláìní fi le di kò-là-kò-ṣagbe, ṣùgbọ́n kí bọ̀rọ̀kìnní àti ọlọ́rọ̀ sì wà síbẹ̀.

Èrò wa ni pé ara àwọn ọlọ́lá ni alákọ̀wé wà ní àwùjọ, onípò sì ni wọ́n, Babalọlá gẹ̀gẹ́ bí ọ̀kan nínú wọn kò lè ní kí ipò agbára parẹ́ ló ṣe ń fi ẹ̀lẹ̀ dá àbá àyípadà. Ìmọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ yìí ló ń fún àwọn aláṣẹ lágbára láti gàba lé mẹ̀kúnnú lórí. Lójú tèmi ẹ̀sìn tó wọ akéwì yìí lẹ́mìí ń bẹ lára àwọn ènìyàn àwùjọ fúnra wọn, èyí tí kò mú àyípadà túláàsì rọrùn. Àwọn ènìyàn tó bá fẹ́ fa àyípadà túláàsì nínú ẹ̀sìn ní àwùjọ wa ń pè ní alákatakítí nítorí wọ́n gbà pé sùúrù ni ẹ̀sìn fi kọ́ wa pé kí á ní. Ìdí nìyí tí àwọn onímọ̀ tíọ́rì ''Marxism'' fi lòdì sí ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn, fún ìrètí òfo tí ó ń fún àwùjọ mẹ̀kúnnù nítorí kí ìlú le rọrùn fún àwọn olórí. Àmúlò iṣẹ́ ọnà bí irú ewì yìí ni àwọn onímọ̀ Mákísíìsì gbà pé a le fi fa àyípadà túláàsì nípa fífi ọrọ̀ rú àwọn òǹkọ̀wé nínú kí wọn fi lè gbé ìgbésẹ̀ fún ìjàjàgbara (Yai 1977:2). Adébóyè Babalọlá fi ẹ̀lẹ̀ dá àbá ìyípadà lásán fún àwọn olóṣèlú nítorí pé kò gbà pé ipá ni yóò fa àyípadà.

A rí i pé bí akéwì yìí ti le wù kó fi ìdí ìgbìyànjú àti àìṣèmẹ́lẹ́ múlẹ̀ tó nínú ìgbésí ayé ọmọnìyàn ibi àyànmọ́ ni yóò fi ọ̀rọ̀ rẹ̀ tì sí. Ọwọ́ Ọlọ́run ni ká kó àníyàn wa lé. Ewì ''Ewu mọ́tò''(30), ''Ọmọdé'' (3), ''Àrẹwà Ọmọge'' , ''Ológbundúku''(24) àti ''Ká ṣe é bó ti gbà''(4) ló fi ìdí èyí múlẹ̀. Ó gbà pé ewúro ni ilé ayé yìí jẹ́ fún ẹni tó ń ṣèfẹ́ Ọlọ́run ṣùgbọ́n adùn ni yóò gbẹ̀yìn rẹ̀ nínú ilé àìnípẹ̀kun lọ́run. Ìgbàgbọ́ ẹ̀sìn yálà ti Àbáláyé tàbí ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn Kristi tàbí ti Mùsùlùmí ló ń mú wa gbà pé a ti kúnlẹ̀ a yan ìpín, a délé ayé tán lojú ń kán gbogbo wa, nítorí náà sùúrù ni a ó ṣe.

Ìlò Èdè

Bí ìsọ̀wọ́ lo èdè rẹ̀ ṣe dùn mọ́ni ló tún tutù mọ́ni, kò le koko, kìí sìí lo èdè jàgídíjàgan. Àwọn onímọ̀ Mákísíìsì àti ìfojú àátò tàbí ìhun wo lítírésọ̀ le má ka èdè rẹ̀ sí ṣùgbọ́n èdè rẹ bá àwùjọ akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn tó nífẹ̀ẹ́ èdè abínibí wọn, tí wọn ń ka ewì fún ìgbádùn lásán ní àkókò náà mu. Ó sì bá kókó ọ̀rọ̀ rẹ̀ mu pẹ̀lú.

Àfiwé pọ̀ nínú èdè rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ látorí àkọlé tó fún ìwé yìí, bí ewé ọ̀mísínmisìn ṣe ń dùn lẹ́nu tó sì ń tu oníkọ́ lára ni ewì yìí ń dùn tó sì ń tuni lára. Àfiwé ọmọdé tó rí ìtọ́jú àti èyí tí kò rí ìtọ́jú ni ''Ọmọdé'', tíṣà àti ọ̀mọ̀lé ló fi wéra nínú ''Ayé ń lọ ní mẹ̀lọmẹ̀lọ'', ọmọge tó kàwé àti èyí tí kò kà ló sì fi ń wéra nínú ''Arẹwà Ọmọge Ológbundúku''. Àfiwé tàárà ló lò jù nínú ewì rẹ̀.

Akéwì kúndùn ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ bí ọ̀rọ̀ orúkọ àti ọ̀rọ̀ iṣe, ọ̀rọ̀ orúkọ 'Akéré-m,á-ṣeé yànjẹ' nínú ''Ohun tó bá yẹ ni ni ká máa lépa'' ló ṣẹ̀dá látara ìwà ẹ̀dá ìtàn ewì yìí.

Àwọn ọ̀mọ̀lé ń dúró de ọkọ tí yóò ''kánàkò'' fún wọn nínú 'Ayé ń lọ ní mẹ̀lọmẹ̀lọ'' sì jẹ́ ọ̀rọ̀ ìṣe tí ó lò dípò ''gbe''.

Òwe sodo sínú ewì rẹ̀, a sì máa ṣe àtòjọ òwe. Ewì rẹ̀ tílẹ̀ máa ń fi ìdí òdodo òwe múlẹ̀, fún àpẹẹrẹ, Òwe ''Ìlera lọrọ̀'' ni ''Ìlera''(29) ń ṣe àtúpalẹ̀. Ó sì ń wa kókó òwe''ojú mẹ́wàá ò jojú ẹni, ṣàṣà èniyàn ní í fẹ́ni lẹ́yìn bá ò sí nílé tẹ́rú tọmọ níí fẹ́ni lójú ẹni'' àti òwe, ''ẹni tí ò sí nílé lewúrẹ́ rẹ̀ bíkan'' gúnlẹ̀.

Ẹ̀ka èdè Ọ̀yọ́ lu ewì rẹ̀ pa bíi 'siàn' dípò 'sunwọ̀n', ìpàròjẹ bíi ''tí an'' dípò ''ti wọn'' pẹ̀lú àfàgùn ọ̀rọ̀ ìṣe ''lọ́ọ́'' dípò ''lọ'' ní ojú ìwé kínínní sí ìkejì ló ti pọ̀ jù. A tún rí ''jọkà'' dípò ''jẹkà'' ní ojú ìwé ọgọ́ta. Èyí jẹ́ kí ewì rẹ̀ jọ ìtàkurọ̀sọ láàrin àwọn akópa tí à ń wò lórí ìtàgé.

Oríṣi ọnà ló fi ṣe àyálò èdè gẹ̀ẹ́sì. Ó yí àwọn sípẹ̀lì ọ̀rọ̀ gẹ̀ẹ́sì kan padà ní ìlànà àkọtọ́ Yorùbá. Ó sì kọ àwọn mìíràn bí elédè ṣe ń kọ wọ́n. Gbogbo ọnà tó gbà lò wọ́n ló bá àsìkò mu. Bí agbẹjọ́rọ̀ ó ṣe sọ̀rọ̀ pẹ̀lú èdè ìperí tó bá iṣẹ́ rẹ̀ mu ni Arábìnrin Dúróoríkẹ̀ẹ́ Olúgbódi ń finú rò nínú ''Àlá ni mo lá''(32):

> Case ti mo gbúròó ẹ̀ fẹ́rẹ́ yìí
> owó ńlá ni n ó fiṣe
> Client táláká kò táláká ìyẹn ò kàn mí
> Kẹ́jọ́ ó mówó wá ni mo mọ̀ (35).

Àdàlù èdè tí àwọn tó gbédè méjì pọ̀ máa ń ṣe nìyí. Ó sì jẹ́ kí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí jọ òtítọ́.

Ó lo ìlànà àfetíyá fún ''Sínóò, Bọ́ọ̀sì, Bọ́ńtińfò, Gọ́tà, Tọ́ílẹ́ẹ̀tì, àti wọ́ọ̀dù'' ''nítorí pé onímọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá ló ń sọ̀rọ̀ nínú àwọn ewì tí a ti bá ọ̀rọ̀ àyálò wọ̀nyí pàdé. Ìlànà àfetíyà ló fi ya ''Kòfẹ́sọ̀'' wọnú èdè Yorùbá nínú ewì ''Àlá ni mo lá'' àti ''Òke Láńgbòdó ni mo rè''. Èyí fi kún àká èdè Yorùbá.

Ọ̀nà mìíràn tí akéwì tún gbà fi kún àká èdè Yorùbá ni nípa lílo èdè Ìkàsì tàbí ọ̀rọ̀ àtijọ́. Ó lo àwọn ọ̀rọ̀ kan tí a mọ̀ àsìkò ìlò wọn, fún àpẹẹrẹ àsìkò kan wà tí à ń lo àwọn ọkọ̀ èrò bíi Bọ́ọ̀lẹ̀ Kájà, Dáńfó, Móòluẹ̀ àti Kórópe(61) ní àwùjọ wa. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọ̀dọ́ kò le mọ̀ àwọn mọ́tò tí ó dárúkọ, ìlò orúkọ àwọn ọkọ̀ àtijọ́ wọ̀nyí á jẹ́ kí wọ́n mọ̀ pé ìyà ọkọ̀ wíwọ̀ ti ń jẹ mẹ̀kúnnù bọ̀ ọjọ́ pẹ́.

Àwọn ọ̀rọ̀ àtijọ́ tí a kò mọ ìtumọ̀ wọn mọ́ pọ̀ nínú ewì yìí, fún àpẹẹrẹ ''Ká tuwo léwo'' (o.i.4) ẹni tí ń rìn lógùntọ́ (o.i.38) ká lòmísì (o.i.40) Ọ̀rẹ́ ìpẹ̀dùn àti Ọ̀rẹ́ minú (o.i.44). Ọ̀nà tí ó gbà lo àwọn ọ̀rọ̀ yìí lọ tàààrà tí ìtumọ̀ wọn kò fi fara sin. Òǹkàwé á le fi kún àká èdè rẹ̀ á sì máa ṣe àmúlò wọn bí èdè awo.

Àwítúnwí lu ewì rẹ̀ pa ní ìbámu pẹ̀lú èdè lítírẹ́ṣọ̀ èsìn, gbogbo ewì ajẹmẹ́sìn rẹ̀ ló ti ṣe àwítúnwí lọ́nà tí kò fi sú ènìyàn tó sì tún ń fi ẹ̀kọ́ èsìn múlẹ̀ síi. Ewì ''Èyí ò yẹ kó rí bẹ́ẹ̀'' tó jẹ mọ́ òṣèlú náà la ti rí àwítúnwí gbólóhùn ''Èyí ò yẹ kó rí bẹ́ẹ̀'' lẹ́ẹ̀mẹta láti fi èsọ̀ yí ọkàn àwọn olóṣèlú padà pé, ó yẹ kí wọn ó ṣe àtúnṣe sí ipò èyìn tí mẹ̀kúnnù wà láwùjọ wa.

Ìfọ̀rọ̀dárà àti ìfìrósínròójẹ kò gbẹ́yìn nínú ewì rẹ̀ lọ́nà tí òǹkàwé fi ń gbọ́ ìró tí ó ń júwe ní etí rẹ̀. Ní ojú ìwé 21, ó ní:

Mò ń gbọ́ ó yá! Ó yá!
Àwọn ọlọ́kọ̀ ló yá nùn un.

Ìró fèrè ọkọ̀ ni akéwì sín jẹ ní ibí yìí. Ní ojú ìwé 60; akéwì ní:

Ìyà ń jẹ mẹ̀kúnnù wọ́n ńjẹ ewé iyá
Mẹ̀kúnnù ń jìyà tó pọ̀ jọjọ
Mèháyà ni mẹ̀kúnnù nínú ìlú ńlá
Bí mẹ̀kúnnù ti mówó osù délé gẹ́lẹ́
Ni ìdá mẹ́ta ńbọ́ sọ́wọ́ aníle-fìháyà
Bẹ́ẹ̀ lórí yàrá kan ṣoṣo ni
Yàrá táyè há gádígádí nínú ẹ̀
Níbití tọkọ taya àti àwọn ọmọ ń háásí.

Àwọn ipò tí ìró ''há, ya'' ti dún ló gbé ìtumọ̀ bí ìyà tí mẹ̀kúnnù ń jẹ ní àwùjọ wa ṣe pọ̀ tó sóde ketekete.

Ọ̀nà tí ó ń gbà gbé ọ̀rọ̀ kalẹ̀ àti ìlò èdè rẹ̀ kò papọ̀ mọ́ tẹgbẹ́. Ó kúndùn kí ó máa ṣe àtinúdá kí a le mọ̀ ọ́ yàtọ̀ sí akéwì mìíràn, àtinúdá ọ̀fọ̀ rẹ̀ fi èyí hàn, dípò tí yóò fi pe ọ̀fọ̀ bí a ti í pè é, ó ní:

''Kíákíá ni mọ́tò rìn
Kíákíá ni kìnnìnún-ún léran bá
Kíákíá lẹ̀kọ̀ èyin náà yóó yọrí sí rere''. (21)

Àbùdá àdámọ́ akéwì yìí ni ọgbọ́n àtinúdá tó fi ń yan àkọlé àwọn ewì rẹ̀, kò jẹ́ kí ènìyàn tètè mọ̀ àkóónú àwọn ewì náà. Ewì kejì, Ìkẹ̀fà, Ìkọ̀kànlá àti Ìkẹ̀rìnlélógún kò fi òye kókó ọ̀rọ̀ àwọn ewì náà han òǹkọ̀wé. Èyí ló sì jẹ́ kí òǹkàwé fẹ́ rí ìdí òkodoro ewì rẹ̀ kí ó tó gbé e sílẹ̀.

Èdè ìmútànsọ ni ọgbọ́n àtinúdá mìíràn tí akéwì yìí lò jù, tí a bá wo ojú ìwé kìínní àti èkejì ní ìbẹ̀rẹ̀ ewì rẹ̀ ''Ìnàjú Ìrọ̀lẹ́'' àti ''Ní Kùtùkùtù Ọjọ́ Kejìdínlógbọ̀n'' bí ìgbà tí à ń ka ìwé ìtàn àròsọ Fágúnwà ló rí.

Àyọlò ọ̀rọ̀ ẹnu ọlọ́rọ̀ bíi ti eré onítàn tún jẹ́ ọ̀nà àrà tó gbé wọ ewì rẹ̀. Bí ìgbà tí à ń ka tàbí wo eré orí ìtàgé ni ewì ''Ọmọ Ọba Hámúléẹ̀tì'' rí. Ìsọ̀rọ̀gbèsì sì ni ''Ọ̀rọ̀ ńlá balẹ̀'' jẹ́.

Ètò ewì Yorùbá ló lò láti òkè délẹ̀, bọ̀rọ̀gidi ló kọ gbogbo ewì rẹ̀. Ìlò èdè rẹ̀ sì ṣe wẹ̀kú pẹ̀lú kókó ọ̀rọ̀ tó ń sọ. Atura ni ewì rẹ̀ jẹ́ gẹ́gẹ́ bí orúkọ ìwé ewì rẹ̀ ''Ewé Ọ̀mísínmisìn''.

Àgbálọgbábọ̀

Nínú isẹ́ yìí a ti ṣe àfàyọ ohun tí ewì jẹ́, a ti rí irú ẹni tí akéwì jẹ́ àti ohun tí a lè pè ní èdè ewì. Àmúlò tíọ̀rì ìfojú ìbágbépọ̀ àwùjọ wo lítírẹ́sọ̀ ti fi hàn wá pé inú àwùjọ akéwì ló ti fa kókó ọ̀rọ̀ rẹ̀ yọ. Àwùjọ tí ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ ara, owó, àti ipò ti ń mú àbúrò pa ẹgbọ́n tó sì ń ba alájọbí jẹ́. Àwùjọ tí ọmọbìnrin ò ti jámọ́ nǹkan kan lẹ́yìn ká lò ó bí i ọmọ ọ̀dọ̀ tàbí aṣẹ́wó. Àwùjọ tí àwọn olórí ìlú ti ń kówó ìlú ná láìbìkítà fún ìyà tó ń jẹ mẹ̀kúnnù. Ìmúdúró àwùjọ ló ń jà fún, kò sì ṣe àfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ yìí lásán, ó pè fún àyípadà pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tútù tó wọ ni l'Ákínyẹmí ara.

Ìwúlò ewì rẹ̀ kò kéré nítorí kókó ọ̀rọ̀ inú ìwé mímọ́ tí a ń gbọ́ lójoojúmọ́ tí kò sì turun kan lára ọ̀pọ̀ ènìyàn mọ́ ni akéwì ń fi ọ̀nà àràmọ̀ǹdà gbé kalẹ̀ tó fi jọ tuntun léti wa. Adùn tí ó ní yóò mú kí

òǹkàwé tún gbà á gbọ́ kí wọ́n sì mú ìmọ̀ràn rẹ̀ sà bí òògùn ju ti inú iwé ẹ̀sìn tó ti di bárakú lọ. Bí ewì Babalọlá ṣe ń kọ́mọ́ lédè ló tún ń kọ́mọ́ lẹ́sìn àti ìwà.

Lérò tèmi, Adébóyè Babalọlá tọ́ ní ẹni tí a le pè ní akéwì alátinúdá Yorùbá tó kúnjú iwọ̀n. Ìpèníjà sì ni iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ fún àwọn oníṣẹ́ lámèétọ́. Oríṣi ọ̀nà ni a le gbà wo ewì yìí, a le wo ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn tàárà, a le fi ojú tíọ̀rì ìṣègbèfábo tàbí ti mákísíisì wo ewì rẹ̀ yàtò sí ojú Sosiọ́lọ́ji lítírẹ́ṣọ́ tí a fi wò ó yìí. Bákan náà sì ni a le ṣe àfiwé ewì rẹ̀ pẹ̀lú akéwì mìíràn.

Ìwé Ìtọ́kasí

Adéyẹmí A. (2001). 'Iṣẹ́ Ọ̀rọ̀ Lámèétọ́ Lítírẹ́ṣọ́ Yorùbá' nínú Àjàyí (Olóòtú) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá Èdè, Lítírẹ́ṣọ́ àti Àṣà*. Ìlọrin.

Akínjọ́gbìn A. (ed) (1969). *Ewì Ìwòyí*. Glasgow: Collins and Sons Ltd.

Babalọlá A. (1969). Ìwà Panságà Láàrin àwọn ẹ̀yà Yorùbá'' nínú *Olókun: Ìwé Àtìgbàdégbà ní Àtàtà Yorùbá* No. 8 (p. 29-30).

Babalọlá A. (1989). *Ewé Ọ̀mísínmisìn*. Lagos. Longman Nigeria Ltd.

Bámgbóṣé A. (1961). Yorùbá Studies Today'' in *Odù*. Vol 1 No.1 P. 85-99.

Caudwell C. (1977). *Illusion and Reliaty: A Study of the Sources of Poetry*. London: Lawrece and Wishart Ltd.

Coulsin J. (1981). *Religion and Imagination: In Aid of a Grammar of Accent*. Oxford, Clarendon Press.

Duvignaud J. (1972): *Sociology of Art*. London: Paladin.

Hamilton E. & Hintington C. (ed.) (1973). *Plato Republic: The Collected Dialogues of Plato*. Princton U.P.

Ìṣọ̀lá A. (1989). ''Koro Jíjá nínú Ìtàn Àròsọ Yorùbá'' nínú Adébáyọ̀ (ed) *Semina ni Ìrántí J.A. Odúnjinrin*. Òde Rẹ́mọ, Odunjinrin Press.

Ìṣọ̀lá A. (1992). *New Findings in Yorùbá Studies*: Ọdúnjọ Memorial Lecture Series.

Jasper D. (1992). *The Study of Literature and Religion: An Introduction*. Hampshire Macmillan Academic and Professional Ltd.

Ògúnsṣínà B. (2000). ''Adébóyè Babalọlá Gẹ̀gẹ́ Bí Òǹkọ̀wé Ọlọ́rọ̀ Geere'' nínú Olútóyè (olóòtú). *Ó Pegedé: Àkójọpọ̀ Àwọn Àròkọ-Akadá fún Yíyòǹbó Ọ̀jọ̀gbọ́n Adébóyè Babalọlá*. Lagos. Longman.

Ògúnṣínà B. (1980). ''Ipa tí àwọn Ìwé Ìròyìn Yorùbá Àtijọ́ Kó Nínú Ìdàgbàsókè Lítírésọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá'' Nínú *Yorùbá Gbòde*. Fol. 1 No. 1 p. 37-53.

Ọlátúnjí O. (1982). *Ewì Adébáyọ̀ Fálétí Ìwé Kejì*. Ìbàdàn: Heinemann Educational Books.

Ọlátúnjí O. (1988). 'Fẹ́mi Fatọ́ba: A New Voice in Yorùbá Poetry' in Owólabí (ed) *Language in Nigeria: Essays in Honour of Ayọ Bámgbóṣé*. Ibadan. Group Publishers.

Oyèláràn O. (2000). ''Adébóyè Babalọlá. Akọ́mọlédè Àríkàwé'' nínú Olútóyè O. (Olóòtú). *Ó pegedé: Àkójọpọ̀ Àwọn Àròkọ Akadá fún Yíyòrìbó Ọ̀jọ̀gbọ́n Adébóyè Babalọlá*. Lagos: Longman.

Sàngótóyè W.O. (1998). Àgbéyẹ̀wò Ọ̀rọ̀ Òṣèlú Nínú Àṣàyàn Rẹ́kọ̀ọ̀dù Láńrewájú Adépọ̀jù àti Túbọ̀sún Ọládàpọ̀. M.A. Thesis University of Ilọrin.

Seldon R. & P. Widdowson (1993). *A Reader's Guide To Contemporary Literary Theory*. Newyork, Hervester.

Yái B. (1977). ''Ideas for a Political Reading of Fagunwa''. Paper read at the Radical Perspectives on African Literature and Society Conference Held at the University of Ibadan.